The Chief Sec To The Government Lagos

# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi"—W. T. Stead.

Vol. II. No. 70. SATURDAY, NOV. 10, 1923. Sixpence

13 NOV. 1923 LAGOS



## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

**"Specialities: Enamelware, Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads etc., etc., etc."**

---

Ọgbẹni **DURO THOMAS**

Cnișowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to ṣẹṣẹ de fun u lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Mãse leti ita Faji, l'Eko.

---

## N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

### J. F. SICK ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode Iailai, l'eti *Glover Memorial Hall*, (*Customs Street*,) EKO.





Awọn Oyinbo Onișowo yi nranșẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1–4 t' ọlwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranṣẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

Awọn Oyinbo yi nṣe orișirisi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranșẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja abọmalọ ati orișirisi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi și nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA.

## J. C. VAUGHAN

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun ẹikele fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

---

## B. O. Joseph

*Commission Agent.*

21 years experience in trade.

- Cotton.
- Sundries.
- Hardware.
- Provisions.

27, Koseh Street, Lagos.

---

## The British Psychological Institute

OF BOLTON, ENGLAND,

teaches by Correspondence the following Sciences:—Psychology, Philosophy, Phrenology, etc., etc.

For complete particulars, apply to the Official Representative of the Institute for Nigeria and Gold Coast Colonies

C. GLADSTONE-MACAULAY,
P.O. Box 384,
Lagos.

*Youngmen, for future's sake, be on the alert.*

## THE LAGOS HOTEL.

Iced Drinks of every description on sale at the above popular Hotel.

Clients' comfort occupies a prominent part in the programme of the establishment.

Billiards playing forming a centre of attraction.

**TERMS :—Strictly Cash.**

H. H. KING
*Proprietor.*

Portonovo Market St.,
Lagos.

---

ILE ERO TI EKO.

Ohun mimu olomi didi to np'ongbẹ enia nbẹ nihin lorişirişi fun tita.

Ko si ọna ti a ko ngba fi tẹ awọn onibara wa lọrun.

*Billiards* idaraya si wa fun ẹnikẹni lati fi şere.– Owo-lọwọ la fẹ.

H. H. KING,
*Oni-nkan.*

Ita Ọja Ajaşẹ, Eko.

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|
| Ọdun kan 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor.*

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

GBỌBANIYI, Ẹ KU'ṢẸ.

Ninu Ipade Igbimọ Aṣofin Ilu ti Ijọba ṣe ni Alamisi (*Thursday*) ọjọ kinni oṣu yi Agbẹjọro-Ọba Donald Kingdon Ọlọla fi awọn Iwe-ofin *Nigeria* ti o ṣeṣẹ ṣe han Ipade na; ọkọkan ninu Iwe na to ẹru ọmọde kekere, nṣe lo ri bọlibọli, lati ọjọ na lọ ni awọn iwe ofin wọnyi ti di lilo jakejado *Nigeria.*

Donald Cameron Oloye sọ pe gẹ'ẹ bi Ipade Igbimọ yi ti jẹ pataki to, o ni inu on yio dun ti a ba le ri ninu awa ọmọ *Africa* ti o ja fafa ninu kikọ'we ni ọwọ kukuru (*Shorthand*) ti yio ma kọ gbogbo ijiyan ipade na silẹ; o ni lotọ awọn kan ti nwọn jẹ ẹya wa nibi nṣiṣẹ na pẹlu itẹlọrun o ni ṣugbọn Oniṣẹ-Ọba ni nwọn; nwọn si ni iṣẹ patẹki nwọn, ti nwọn nṣe ni ibi iṣẹ tobẹ ti eyiti a pe nwọn si pe ki nwọn wa kọ ohun ti o ṣẹlẹ ninu Ajọ Igbimọ (*Minutes taking*) ti a ṣe ni lọlọyi silẹ ni ọna *Shorthand* le jasi idiwọ fun wọn fun iṣẹ wọn papa. Ṣugbọn Ọgbẹni Ajasa Ọlọla ni, nitori on, Oyinbo ni on fẹ fun iru ipo ti Comeron Oloye na wi yi.

Ọgbẹni Shyngle Ọlọla bere bi a ko ni ma tẹ gbogbo Ijiyan (*Debates*) ninu Igbimọ na si *Gazette* Iwe Irohin ọsọsẹ Ijọba fun kika gbogbo enia? Cameron Oloye si fesi pe bi Ajọ Igbimọ na ti nṣe si ni Ijọba yio tẹ fun kika olukuluku enia; inu awa ti a wa ni Ipade yi lọjọ na si dun gidigidi fun esi yi.

EYI ṢO NI LỌWỌ!

Ohun iyanu nla li o jẹ fun ni lati gbọ pe awọn Alaṣẹ *Church* C. M. S. nibi da Alufa wọn kan ti o wa ni Ijọ kan nilẹ yi duro fun Iwa afọwọra ti a sọ pe a ri lọwọ rẹ nipa owo ko ṣe owo: eyi jẹ ohun ibanujẹ fun ni, ko si yẹ ki a ma yọ si nkan bẹ biotilẹjẹpe a ko le fọwọ tẹ ẹniti o ṣe irufẹ ẹṣẹ bẹ nidi; ẹtẹ awo sa ni ẹtẹ Ọgbẹri "Ẹ jẹ ki ẹniti o rope on duro ṣọra ki o ma ba ṣubu" ki Baba ṣọ ni!!!

EGUN TI A SO M'AJA LORUN
O SI NSAN?

Ọkọnrin kan ti a sọpe Ọgbẹni T. A. Ẹmnoṣo fun ni ẹrọ ikọwe (*Type Writers*) meji fun lati tunṣe, ta ọkan ninu rẹ ti iye rẹ jẹ £47 ni £7 o si san £2. 5. o. gbese to jẹ ẹnikan ninu owo na; o si sọ pe ki a fi owo to ku di igbese ti on jẹ ẹlomiran. A ki ọkọnrin yi mọ'lẹ lọ si Ṣabu awọn Ọlọpa lati ibẹ lọ si Kotu Adajọ kekere nibẹ ni a gbe fi si ẹwọn oṣupa mẹta, pẹlu iṣẹ aṣegan; lẹhin igbati o ti jẹbi ẹsun na.

KOTA, KORA, KO M'OKAN WỌ'LU,
ALAKORI NFA ẸṢIN ẸLẸṢIN LỌ.

Bẹ si ni Adajọ ju ọkọnrin kan ti o lọ tu ẹṣin ẹlẹṣin kan lori iso lati lọ ta ninu ọsẹ yi si ẹwọn oṣupa mẹta pẹlu iṣẹ aṣegan nigbati o jẹbi ẹ̀sùn ole na tan niwaju Adajọ. Eyi kèlè o!

BABA WA TA NWI, BABA WA DE.

Tayọtayọ la fi ṣalabapade Baba wa nipa ti Oluwa eyini ni Bishop Oluwọle ni 'le ọrẹ wa kan ni *Sunday* tokọja, Baba wa na ṣeṣẹ tokunbọ wa 'le lẹhin igbati o ti lọ sibẹ ni li'e ni oṣu meji tokọja nigbati o fẹ si diẹ; ẹrin ọyaya baba wa yi jẹ kolẹgbẹ: nigbati o si sọ pe kosi "*Eko Akete*" ti o ma jade lọsẹ kan ti on kò ri kà, ori wa wu

Alagba, "Gbogbo nkan wọnyi ti ẹnyin nṣe ni awa ri, awa si dakẹ" ; awa o ba nyin sọrọ, a o si ma ka a li ẹsẹsẹ niwaju nyin.

SAMUEL—*Wolî kekere.*

## *EKO AKETE.*

EKO, SATURDAY, NOVEMBER 10, 1923.

### O ṢE, ARAKỌNRIN MI!!!

Ayá ọla jẹ ọdun karun gbako ti ogun Ajakaiye to bẹrẹ ni ọdun 1914 ni Ilu Oyinbo to si kan wa nibi pari ; nitorina o jẹ aṣa ti Ọba *King* da silẹ ni Ilu Oyinbo pe o yẹ, o si tọ jọjọ lati ṣakiyesi ọjọ na nipa pe ki gbogbo agbaiye duro si fun iṣẹju meji ni agogo mọkanla arọ lati fi ọkan gbadura fun ogunlọgọ awọn akọni wa, ibaṣe ni iha *Nigeria* wa nibi ni, tabi ni Ilu Oyinbo ti nwọn ti fi ẹmi wọn lelẹ fun emi ati iwọ ninu ogun na ; Ijọba wa si fi aṣẹ si imọran daradara yi, eyiti ẹ o ri ka lapakan Iwe-Irohin yi ninu "waya" ti ọga awọn Gomina fi ṣọwọ si Gomina nibi lede Gẹsi ; nitorina, a sọ fun ẹnyin ara wa pe nigbati o ba ti di agogo mọkanla arọ ọla na, ti ẹ ba si gbọ iro agba, ki olukuluku nyin dide ki ẹ si tọrọ adura kẹlẹkẹlẹ fun awọn enia wa wọnyi bẹ gẹgẹ, ki ilu si parọrọ. Tiwa t' ayọ nitoripe bikoṣepe awọn ogunlọgọ ninu awọn ara Ilu Gẹsi ati awọn enia wa nibi lọ ta ẹjẹ nwọn silẹ ni, ki a to ṣẹgun ọta eyiti iṣe awọn Gamani, nibo ni a o ru wọ nisisiyi ? Boya diẹ ninu wa yio niran igbati a gbọ idagiri kan ti ọkọ jomi-joke ( *Submarine* ) ti awọn ọta lọ da ilu Liberia ti ko jina si wa nibi ninu oṣu *April* ọdun 1918 nipa rirọ agba si ilu na, bawo ni idamu na ko ti pọ to ni ilu yi ? ṣugbọn a dupẹ pe awọn Ijọba wa ko fi igbakan dẹ ara silẹ fun awọn ọta nitoripe lọgan ni Ijọba wa ti dubu ewu ti a ni ireti nigbana pe boya o le ba wa l' Eko nibi titi ewu na si fi rekọja lọ ; a dupẹ pe loni ko si ogun bẹni ko si si ọtẹ mọ ; nitori eyi papa lo yẹ jọjọ ki a ni ẹmi idupẹ lọdọ Olodumare pe ki aiya ilu maṣai ma balẹ titi, ki o si dẹlẹ fun awọn to ti ba ogun na lọ, tabi awọn ti o ti di alailera nipa gige apa, ẹsẹ, tabi fifọ oju ninu ogun na. Ewo ni ko to ro nibẹ ? ti awọn ara wa to ku si ogun *Cameroon* ni ko to ro ni, tabi awọn to ku si *East Africa* lẹhin igbati a ti ṣẹgun awọn ọta tan ni Ilu *Cameroon* ti a si tun ṣigun ti *East Africa* pẹlu ? Ni ko iti pẹ yi ni Sẹkitẹri Agba ti Ijọba, Donald Cameron Oloye K.B.E., sọ ni Ajọ Igbimọ titun ti a ṣẹṣẹ da silẹ ni lọlọyi pe o to ọkẹ marundilogoji pọun ( *£700,000* ) ti ogun na na wa ni *Nigeria*, ki a ma ṣẹṣẹ sọ ti ẹgbagbeje ẹmi ti o ba rin mọ, ibaṣe nibi, tabi ni Ilu Ọba ; gidipa nigbati a nda owo ogun nigbana, ẹnyin ara wa yio ranti pe ni ọdun 1917 Eleko Ọmọ Alade ( *Prince Eleko*) paṣẹ ki a ko Ẹyọ fun awọn enia wa t' oyinbo t' enia dudu to ṣubu loju ija na, Ijọba si yọda eyi ; l' ọna yi, o ni iye owo ti Eleko kojọ fun dida sinu apo Ẹgbẹ Ogun kan ni Ilu Oyinbo ti a npe ni Ẹgbẹ Agbelebu pupa ( *British Red Cross Society* ) Ilupesi ni a tẹ "Oku" awọn akọni na si ; a si niran orin ti a nkọ kiri fun Ẹyọ nigbana bayi :—

> Ọlọrun Ọba ye—
> Ọlọrun Ọba jọwọ o
> Jẹ k' a rowo sinku Oyinbo
> to ku sogun o.
> Oke rere Ọmọ Ọba, a nlọ
> m' Oyinbo bọ
> A nlọ m' Oyinbo bọ wa 'le, a nlọ
> m' Oyinbọ bọ ;
> Oke rere Ọmọ Ọba, a nlọ
> m' Oyinbo bọ.

Apọnran ati iya ilu to nfọgede lọjọ Ẹyọ na, jẹ ohun ti ẹnikẹni ko le gbagbe titi lai.

Irufẹ eyi fi han ni pe ko si ẹniti ogun na ko kan nigbana ti dudu ti funfun ; bi Ijọba ba si fi aṣẹ si pe ka fi aye iṣẹju meji pere silẹ lọla lati ṣe iranti awọn ara wa Akọni wọnyi a ko ro pe eyi na buruju.

Nitorina a tẹ mọ ẹnyin ọkawe wa leti ki ẹ ma ṣai ṣe bi a ti wi ni ọla na, bi a ko tilẹ le san rere ti awọn enia wa wọnyi ṣe fun wa nipa fifi ọrun gba ida ni gbogbo akoko ogun na fun wiwalãye temi tirẹ loni

fun bibọ ti nwọn mu wa bọ loko ẹru Jamani, ti a ba nṣe iranti wọn bayi lẹkọkan lọdọdun gẹgẹbi Ijọba ti lana rẹ silẹ fun ni, a o jẹ ẹniti o mọ õre, a o si ni ẹmi Imọriri nkan ati ẹmi Idupẹ.

---

## NIGBAWO NI AWỌN ṢAKITI YIO JI DIDE LORI IBUSUN WỌN.

Inu wa dun pupọ lati fi han awọn Imale Ẹgbẹ wa pe imọlẹ nlanla bọ si arin wa, okunkun si salọ.

A gbọ pe awọn Ijọ Imam Ratibi ti Mọṣalaṣi Oni Jalailu, wọn gbiyanju lati mú da owo lo ṣoṣu lati fi san owo fun awọn *Teacher* to nkọ awọn ọmọde ni Ile Ẹkọ Mọṣalaṣi Shita ati ti Animaṣaun; o si le ni 500 ọmọde to nkọ ede Larubawa ati ede Gẹsi. Oluwa ko ran awọn Imam Ratibi wọnyi lọwọ.

Awọn Ijọ Ammadya nsunrajọ lati kọ Ile Ẹkọ si oke Ẹlẹgbata fun awọn ọmọde, Ile Ẹkọ meji ti wọn ni nisiṣiyi, o le ni 600 ọmọde to wa nibẹ, gbogbo wọn lo mọ itumọ kewu pataki ti wọn fi kirun si ede Yoruba. Igbadun rẹ pọ.

O jẹ ayọ nla fun wa lati sọ pe awọn Imale Ebute Mẹta ki ṣe eleti didi, wọn ki ṣe agbọ ma gba bi awọn Ijọ ẹlẹgbẹ wa to wa lati de Araromi Odo, wọn ti yan Alufa mẹrin to mọ Kewu dada lati sọrọ Ọlọrun fun wọn. A nireti pe awọ agbagba Ijọ ko ni kandi mọlẹ si Iyara ni ọjọ Wasi.

A si gbọ pe awọn Ọdọmọdekunrin to mọ Iwe Gẹsi to sin gbọ ede larubawa bi omi, omiran ninu wọn jẹ Allaji, wọn ṣara wọn jọ lati ṣe Ẹsin Ọlorun lọna dada ju ti awọn agbagba lọ, wọn lẹ lati kọ Ile kewu ati Iwe pọ, ki wọn sin fi ẹsin han wa dada ni Ede Ilu wa, ki gbogbo wa sin gbọ ede Larubawa lagbọye. A ro pe awọn agbagba ki yio mu wọn lọta. Yio sin dara pupọ bi awọn papa ko ba fi ọtẹ ṣe akojọ na. Oluwa ko ran wọn lọwọ

A fi eti si ode lati gbọ ọna ti awọn Shakiti ngba lati tan ọrọ Ọlọrun ka gbogbo aiye.

Gẹgẹ bi awon Amadia ati Ijọ Onijalailu ti san ṣokoto giri ti wọn sin ntan ọrọ Ọlọrun ka aiye. Ẹlọ bẹ awọn ọmọde wo ni ita Balogun ni agogo mẹrin ọjọ ọsẹ kẹ sin lọ wo ijo Amadia ni Bangboṣe Street, ẹlọ wo Mọṣalaṣi Animashawun ati ti Shita ni ọjọ *Monday* bo ti kun fun awọn ọmọde to nkọ ẹkọ, a ko le sọ ti Mọṣalaṣi Amadia ni Aralọya ati Bangboṣe Streets, ọrẹ mi, sọ fun mi, nigbawo ni Shakiti yio ji dide kuro ninu orun wọn tabi odi Alaira?

Gbogbo awọn ọmọde to wa ni abẹ Ile Ẹkọ awọn Amadia ati Ijọ Jalailu Dini odin diẹ ni 1200 ọmọ, laikan eyiti o wa ni abẹ Ijoba ni Ọnala. A nireti pe Shakiti yio fi to 500 ọmọ si Ile Ẹkọ ti wọn laipẹ ati pe awọn Imam Ratibi ti wọn yio ṣe idawo oṣoṣu bi Ijọ Jalailu Dini lati san fun awọn Olukọ ( *Teachers;* ) O ku sọdọ yin nikan.

AJILARAN.

---

## THE NIGERIAN LEGISLATIVE COUNCIL ELECTION.

[ *Continued from our last issue* ]

Why should it be suggested that those who form this political party are of the worst in the community whose villainy knows no depth? Or why should it be given out as of the voice of an oracle that because the people have chosen their representatives from the Democratic Party, the election scheme has failed?

We would refuse to believe such rank pessimism bordering on conceit. We would rather suggest that the election would have completely lost its lasting effect, if it failed to convince those whose defeat at the election has naturally caused disappointment, of the stern necessity for combination and living for the public good. We do not think their defeat is too costly a price to be paid for failure to have learnt sooner what tremendous odds were against them by their divisions and disintegrating tendencies. We may therefore be permitted to congratulate the successful party on being able to muster solid a phalanx and prove the mettle by such outstanding victory. We need hardly say that it should be their chief purpose to refute the dreadful allegations with which they have been dubbed, by proving themselves worthy of the confidence their people have reposed on them; as also be of great service to government. Certain recent acts of lawlessness have been committed and there have also been manifested feelings of callous jubilation which have led us to suspect that the people are getting desperate. In a community as Lagos, where we are told the mass of the people are illiterate it should be the duty of those educated, in all their actions, especially such as concern the public welfare, to go warily and with great circumspection. A policy of wrong doing—abusing confidence and of taking mean advantage over a section of the people because they are weak and illiterate may produce such acts of lawlessness and disorder which we are sorry have occurred at Lagos. We would therefore entreat our Brethren to ponder over the events of the last few months and instead of their leading to recrimination or censoriousness, let each look well to his own personal obligation and see to it that he is on the right track to bring about peace and good understanding amongst all classes. We trust we shall be gratified to learn that a new orientation has dawned on the leaders of the Nigerian Community and that with the new Legislative Council, they are on the way of rehabilitating their social manhood, establishing peace and contentment amongst themselves which will greatly enhance the economic potentiality and social dignity of Prosperous and United Nigeria. Long may Nigeria Flourish! Long may she prosper!—*Sierra Leone Weekly News.*

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo ukoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ.
6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)
Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)
MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m.—St. Paul's (Breadfruit) | | J. M. Ologundudu |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero) | Arch. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. H. V. E. Johnson |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev. J. A. Leigh |
| 6.30 p.m. | | do. |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m | Tinubu | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | do. | ,, A. N. Cole |
| 10.30 a.m. | Ereko | do. |
| 7 p.m. | do. | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | do. | Rev. J. A. Angus |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | ,, D. A. Bababunmi |
| 7 p.m. | do | Rev. S. A. Pearce |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. M. B. Newton |
| 7 p.m | do. | Rev. J. F. Ogunko |
| 9 a.m. | Erelu | Bro. A. M. Williams |
| 7 p.m. | do. | Bro. J. A. Laleye |
| 9 a.m. | Bethel | ,, A. Ọbadina |
| 6.30 p.m. | | Rev. E. A. Akinọla |
| 9 a.m. | Zion | Bro. A. O. Thomas |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. N. J. D. Shomuji |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. O. Ajayi |
| 4.30 p.m. | | Rev. I. O. Oyekunle |

**FIRST BAPTIST CHURCH**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. A. T. Openiyi |
| 6.30 p.m. | | Rev. J. R. Williams |
| 9 a.m. | Ararọmi (Baptist) | Bro. J. F. Oṣodi |
| 5 p.m. | | Bro. Joseph Bandele |

**EBENEZER (BAPTIST)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Bro. Jeariọgbe Tubi |
| 6.30 p.m. | do. |

**BROTHERHOOD**

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m. Ilupesi | Adelani Gbogboade |
| 7 p.m. | Prof: Adeoye Deniga |

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Rev. A. Adekoya

**AHMADIA (ISLAM)**

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajose (Bamgboṣe Street.)

**COLONIAL CHURCH (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion
6.45 p.m.—Evensong and Sermon, Rev. H. A. Lewis

**SALVATION ARMY.**

10 a.m. (HARVEST) Lieut-Colonel Geo: H. Souter
3 p.m. & 7 p.m. do

**CHURCH OF GOD**

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square
Edwin Mathew & Wm. C. T. Todd

---

ABỌ O.

A ki Ọgbẹni wa B. C. Vaughan ti Agarawu kabọ lati ilu Ọba, bọkini na ọkọ *Wahehe* de l'ọsẹ yi. Ẹ ku afẹ...

---

Orin ti Biṣi kọ nigbati a ṣoku Mam Ṣapara Williams, Iya Lawyer K... ati Dr. Ṣapara awọn Ẹgbọn M... Nancy Edwin Cole l'Eko ni O... 1896.

Ijẹṣa ni Kirisi
Tẹjumade l' ara Agọ owu (2)
Ọmọ-arẹ ma ta yi, ma ta yi o.
Ẹpo wọ nu' lẹ lọ yọ (2)
Ijẹṣa ni Kirisi
Tẹjumade l' ara Agọ owu.

[A dupẹ lọwọ Ọgbẹni Simmons Olowo... No. 3 ita Layẹni l'Eko, fun orin yi ti o fi wa—Ed. Eko Akete.]

LAGOS STEVEDORING COMPANY.

**ALL STEVEDORING WORK**

undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

**GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.**

Estimates given for the handling of goods under any circumstances.

*PRICES ON APPLICATION.*

TO

**S. I. M. Johnson,**
9, Scale Square,
Phone 227 Lagos,
P.O. Box 498.

---

## *Wool, Wool, Wool.*
## *Silk, Silk, Silk.*

Wulu tabi Siliki lo nfẹ ra ọmọ iya mi? Lọ si Ṣabu Iya Labu, nibẹ ni iwọ yio ri ni oriṣipe, Wulu ati Siliki lo fi ṣiṣẹ ṣe—Kọbọ ẹru.

(Abulati mbẹ pẹlu bi tẹdi, ọmọ iya Siliki ni.)

18 & 137, Victoria Street.

---

ẸNIKEJI,

Aṣọ Oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku Ọyọku ni owo wọn, lọ berẹ ni 3 St. John Street, l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

---

FOR SALE

One upright grand Iron-frame Piano, with beautiful tone. New condition—Owner going on leave, and will repurchase on his return six months.

For Terms, etc., apply to the EDITOR.

---

**JUST THINK OF THAT.**



Persons desirous of selling or acquiring Houses or Land in the Colony of Lagos should communicate with

E. SOYEMI ALDER

who for many years has specialised in this class of Property. Sales effected by Public Auction or Private Treaty. Valuation for Mortgage or Probate carefully prepared. Loans arranged Commissions reasonable.

☞ Please note address:—E. SOYEMI ALDER, Auctioneer, Valuer, etc., Owode (opposite the Law Courts) Tinubu Square, Lagos.

---

**The Union Night School.**

FOUNDED JAN. 1923.

The School prepares candidates for Cambridge, Preceptors and Government Clerical Examinations and also teaches all Infant and Primary subjects, Yoruba inclusive.

The School opens on Mondays, Wednesdays, and Fridays in the Breadfruit School (Top floor) For further particulars apply to

*THE SECRETARY,*
Union Night School,
P.O. Box 121,
Lagos.

---

ILE IWE ALẸ.

A da Ile-iwe alẹ silẹ fun gbogbo ọmọ Ile-iwe ati oṣiṣẹ pẹlupẹlu fun awọn ti o nfẹ lati ṣe idanwo fun iṣẹ Ọba ati *Cambridge*, a si nkọ iwe Yoruba nibẹ. A nṣe Ile-iwe yi ni ọjọ *Monday*, *Wednesday* ati *Friday* ni agogo meje abọ alẹ ni Ile-iwe *Breadfruit* (Loke.)

## AWORAN ALARABARA.

A ni Aworan oniruru fun tita lati fi şe ile l'ęşọ. A ni ti titę oku Jesu, ti igbati a da a lębi iku, ti onję alę ikęhin, t'owo lowo, a ni ti Adam ati Efa, ti işędalę aiye, ti Nebuchadenezar nigbati o wa ninu ọla ati ijọba rę ati nigbati o di ęranko, ti obinrin ti o fi ọwọ mu ejo, ti Ọba Tatambulu.

Awọn Aworan wonyi mbę bi aba, nwọn si pọ tase. Bi o ba fę ko pupọ, a le din ọ ni owo dię ki o ba le ri tirę ję. Iye owo wọn 3d, 4d, 5d, 6d, fun ọkọkan. 2/6d, 3/-, 4/-, 5/6d fun mejila tabi *dozen*.

A ni Ewe-taba fun kika ta, Ọşę-ọlowọ agaga, Iyọ-iyọ mbę lowọ bi wọbu, bi o ba fę tọn a le ta a fun ọ, Işana alapoti fun tita ko si bi a ti nşe wọn, orişirişi ọja lo wa lọwọ wa, iwọ ko le ba wa şowo ko ma ri tirę ję, nitori owo pọku ni a nta wọn, owo ọja wa rọju rekọja ala. Bi o ba wa si ile Ọja wa, kami-kami ni gbogbo wọn, bi o ba fę ja iyọ wa, rin wa sibę.

Ibikibi ti o ba ngbe ni *Nigeria* tabi ęhin okun kọwe şowọ yala ni ede Gęsi tabi ti Yoruba si :—

E. O. AMBĘ & BROS.,
38, Moloney Bridge Street, Lagos,
( *Lęgbę awọn On şowo A. J. Iangalakis* )
Idumagbo.

---

## ỌJA ỌPỌ

Ni ile Egbogi nla ti Filipi ti a npe ni :—

**PHILLIP'S MEDICINE STORE**

ni Ajęlę, Ita Faji, Ita Balogun ati ni Ebute Męta ( Ibadan Street )

A o bęrę si ta opọlopọ Egbogi iyeb'ye eyiti awọn enia ti o mọ tobę ri, ati awọn miran ti o ję Egbogi titun ni ọpọ lati ọjọ *Monday* ti o mbọ yi lọ, fun igba diẹ.

Orişi awọn Egbogi na pọ ju eyiti a le ma kọ silę ninu iwe yi, bęni ędin owo ori wọn si pọ to. Sa wa wo wọn,

Ọpọlọpọ Egbogi miran ti o ti mọ ri ni õ si ri ra ni ọpọ pęlu.

---

## NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

---

## AKIYESI.

Ti ę ba fę lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja ninu Iwe-irohin yi, ę jare ę sọ pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ę ti ri ipolowo ọja na ki.

---

# JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 30, Dosunmu Street, Lagos, ...

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

---

## OGUN YANMUYANMU ATI EŞINŞIN.

( *Fly Catcher.* )

Eşe ti o fi nję ki Yanmuyanmu ati Eşinşin ko arun ba ọ, nigbati ogun rę wa ni arọwọto rę. Ęgbęrun pere ni (3d.) Ędęgbarun fun mejila ( 2/3d a dozen )

A si ni ipari olorun amu irun di daradara, o si ma nję ki irun sunmọ, nję ki o ma kọmọna bi jigin, ari malęhin pada ęhin. ( *Hair preparations.* )

Kọwe tabi bere l'ọdọ

DIPO TUNDE & Co,
P.O. Box 335,
30, Victoria Road,
Lagos, Nigeria.

---

## A CHANCE FOR THE FIT IN THESE *HARD TIMES* !!!

Wanted, a good Salesman capable of managing

***A Goods Shop***

*Salary Liberal.*

Only those with substantial Security need apply to the EDITOR of this paper.

---

*Ibi ni ęnyin ro si mi—Şugbọn Oluwa mọ si rere*

ỌKANLAWỌN BALOGUN BROTHERS

Dealers in best quality of Produce viz:—Cocoa, Kernels, Palm Oil, Skins of any kind etc., etc., etc.

*Head Office* :—16, BANKOLE STREET, LAGOS.

*Branches at* :—Lagos, Agege, Agbado, Ifọ, Ilọrin, Wasinmi, Owowo, Ilara, Lafenwa, Ibadan, Ileigbo, Iwo, Ikirun and Oshogbo.

*A trial order will be thankfully solicited.*

---

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.